**Owe**

Adię ìba l'ọko, ìba l'atitan ṣe nkan. Imado ìba ṣe bi elede a ba'lo je. Ęru ìba l'ọba, enia ko ba ti ko okan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jẹkí Fenia sunwọn, Feni ma sunwọn ko ni gbọ. Apa ọmọde ko le ka igi Ona, yio ma doyika.

VOL. XII No 672 LAGOS. SATURDAY NOVEMBER 19, — NOVEMBER 25.. 1960. KỌBỌ MEJI (2D)

# OMO ENIA DUDU DI GOMINA - GBOGBO - GBO ATI ALASE PATAKI ILE NIGERIA

EKO — Ęgbę-gbęrun awọn enia ni o yọ ṣẹṣẹ. nigbati nwọn fi Dokita Nnamdi Azikiwe bura fun oye nla ti Gomina - Gbogbo-gbo ati Alaṣẹ Pataki fun ilẹ Nigeria ni gbangba tẹju Tafawa Balewa Square, (Race Course) ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ọjọ kẹrin-di-logun oṣu November, 1960.



His Exellency, The Rt. Hon. Dr. Nnamdi Azikiwe

Ninu ọrọ re ti o fi "Igbolafia awọn enia laye" (Respect for Human Dignity) ṣe akole re, ni o ti kesi gbogbo awọn Alakoso ipinle ijọba ile Nigeria metẹta wipe, ki nwọn gbagbe ohun ti o ti kọja, ki nwọn sowọpọ pelu Olotu Ijọba Apapọ Alhaji Sir Abubarka Tafawa Balewa ati on ninu iṣẹ nla pataki fun atunṣe ati gbe ilu wa duro, ti o jẹ iṣẹ ti o mbẹ niwaju wa. O tun sọ siwaju wipe ko si ohun ti o le mu wa gba pe, iran enia dudu je ero ẹhin si awọn iran miran.

Eyi ni ọrẹ ati aladugbo rẹ fi orukọ rẹ ṣe ni ede Oyinbo.

## Congratulatory Accrostic

N - Now is the time to enjoy freedom fought for without bloodshed

N - No more shall Colonialism rear its horrid head in Nigeria

A - Amidst sons of Nigeria shall peace and happiness reign supreme

M - Mainly to proclaim the erstwhile glory of their forebears

D - Destined to be the heritage of children yet unborn

I - Interwoven with tranquility, sincerity of purpose and blissful life

A - Astute politically sagacious figure acclaimed by friends and foe

Z - Zealot of political risorgimento, economic determinism and religious emancipation

I - Indefatigably redoubtable in his quest for freedom for Nigeria

K - Keen Advocate of fundamental human rights

I - International Journalist of inestimably high repute

W - Welcome our first African Governor - General and Commander-in-Chief

E - Embraced by all sons and daughters of Nigeria- our Motherland.

FLOREAT NIGERIA

By a friend an erstwhile neighbour.

## Ijoba Iwo-orun Yio Pese Omi

ỌYỌ — Oloye S. A. Tinubu ti o jẹ ọkan ninu awọn Alakoso Ijọba Iwọ-orun ni o sọ fun wọn ninu ipade igbimọ ibilẹ i u Ọyọ laipe yi wipe ijọba Iwọ-orun ti a owo ti o le ni £140,000 lori iṣẹ omi fun ilu Ọyọ, yio si tun na owo £108,000 si lati fi pari iṣẹ omi na.

Oloye Tinubu tun sọ pe ijọba Iwọ-orun ti na owo to lẹ] ni £300,000 fun omi ni agbegbe Ọyọ, yio si tun na si awọn ilu yoku.

# Ewon Odun Meta fun Ole Kuramo

EKO- Awon jaguda pati baba bilisi, ti won ma rja won l'egun ni Ode Kuramo ni owo te ohun ninu won ti adajo se si ewon odun meta.

Odaran na pe ara re ni Onise-ero ti oruko re nje Ganiyu Agbonmagbe, on ni awon Olopa mu wa siwaju adajo fun esun ole jija, wipe o ji agogo owo ati apo kekere kan ti o je ti Ogbeni J. H. Jones, Oyinbo Olotu ile owo (Bank Manager) ni ojo kedogbon osu September 1960.

Agbonmagbe gba pe [illegible] ni on [illegible] Awon olopa so fun adajo pe Onibara awon ni Ganiyu Agbonmagbe. Adajo se idajo re bi a ti ko si oke iwe yi.

# Adajo Ko Gba Iduro Eiye-inu-Ogba-Ewon.

EKO- Yesufu Animashaun, ti awon olopa pe ni Eiye-inu-Ogba-Ewon ni awon mu wa siwaju adajo fun esun wipe o ji awon ohun ti o to pounn meta ati sile mejila.

Animashaun ti se ewon ri o si ise ewon odun meta lowo ninu ogba ewon ni "Kirikiri" ni awon tun mu wa siwaju adajo wipe o wole Ogbeni Charle [illegible] No. 6, Ayenuga Street, Mushin ni ojo kejidinlogun osu May, odun yi o si ji bata ti nwon npe ni Bally Shoe kan, ati e a Soti Sakota kan, apapo owo gbogbo re je £6 : 12s : 0d

Odaran na ni on ko jebi. Adajo ko si gba iduro fun. Adajo se tiro ejo re si ojo kefa osu December odun yi.

# Oloye Akintola Se Aponle Gomina Agba

IBADAN - Nibi apeje nla kan ti Ijoba Iwo-orun fi se ti fun Gomina Agba ti o gba isinmi afehinti nilu Ibadan ni asiko ti o le dagbere fun won, ni Olori Ijoba Iwo-orun Oloye S. L. Akintola ti

( Wo yoku loju ewe keje )

# OGBENI FELA SOWANDE NILU OYINBO



Ogbeni Fela Sowande ti a nwo aworan re yi ni eniti o ko opolopo orin, ti o se eto [illegible] ni Bournemouth Gbangan nla kan Hampshire, England.

Awon Oyinbo ni nwon lo Isinko ti ile Nigeria gba ominira ni ojo kini osu Oct. 1960, [illegible] Ogbeni Sowande yi ni oga kan ninu Ile-ise ero Asoro magbesi ilu Eko.

# Ejo Apania Bere Ni Kotu

EKO -- Okunrin ti o nje Okisamen ti o lo gun awon enia meta l'obe ninu ile No. 14 Patey Street, l'Eko ninu osu May ti odun yi ni nwon bere tiro iwadi ejo re ni Kotu Yaba.

Eniti o koko jeri ni Sunday Tatie, o so ni Kotu wipe Raymond Okisamen gun egbon (okunrin) obinrin ati iya won ti o sun lobe ni oju-orun. O tile le on na barabara sugbon owo re ko te on.

Odaran na koko da ijongbon kan sile ni Kotu nipa kiko pe on ko ni si fila ori on silę, o si tun fe joko, nigbati ko ri apoti ijoko, o gbe aga kan nibi ijoko awon Loya, eyi di fa mi ki nfa e pelu awon olopa. Ni ikehin, o joko sile nigbati won ko je ki o gbe aga ijoko na titi ti adajo fi ye ejo re sigba miran.

Adajo ti so wipe ki nwon ko mamu'ko da si lowo, nigbati o woye isesi re.

Eniti o tun jeri ni Christiana Kevbede, arabinrin okunrin ti o ku o so ninu eri re pe odaran na je eniti on nfe ni oko on si ti pete igbeyawo pelu re sugbon awon obi on ko ati arakunrin on ti o ku na ko pelu, o so pe odaran na damoran ati gbe on salo si ilu Ghana sugbon on ko gba.

Christiana tun so pe ni [illegible] karun osu May ti odun yi ni odaran na wa ba on, o si mbere ewu awotele re nigbati on ko ri on fe san owo 4s 6d fun dipo ewu awotele, odaran na ko jale o si gun Samuel lobe ni agbede ikun, o si ku ni Ile iwosan.

(Wo yoku loju ewe keje)

## Ebun Awo Wura

EKo-Ni aṣalẹ ọjọ Jimọ (Friday) ọsẹ tokọja, ọjọ kọkanla oṣu yi, ni Olotu Ijọba Apapọṣe, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, gbe Awo Pakata Wura kan le Ọlọla Gomina Agba ati iyawo rẹ lọwọ gẹgẹbi ẹbun imore gbogbo iṣẹ ti nwọn ṣe fun agbega Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria fun ọdun marun ti ilẹ Nigeria fi le gba Ominira ni asiko iṣẹ ribiribi wọn na.



Sir James Robertson

Ọrọ ti nwọn kọ sinu Awo Pakata Wura na niwọnyi:- gẹgẹbi awa ti le tumọ rẹ: "Eyi ni ẹbun ti Ijọba Apapọṣe fi ta



Alhaji Tafawa Balewa

Gomina Gbogbo-gbo ati Ọlọla iyawo rẹ lọrẹ ni iranti iṣẹ ribiribi ti nwọn ṣe ni asiko ọdun marun ti nwọn fi ṣiṣẹ fun idagbasoke iṣelu, iwa rere ti nwọn fi mu ki ilẹ Nigeria le di ominira. ọgbọn wọn, imọran ati inu rere wọn pẹlu ifẹ ni o jẹki gbogbo enia Nigeria ma b'ọwọ fun wọn"

November 1960.

## Ibo Ti Nwon Di Nile America F'ore Fun Kennedy

AMERICA - Ninu iporogan ibo ti nwọn di nilẹ America fun enia meji lati yan enia kan si ipo Alakoso ilu Amerika (President) awọn enia meji ti nwọn ta iporogan ibo na ni Ọgbẹni Richard Nixon ti o jẹ Igbakeji Alakoso ilẹ Amẹrika ti o fẹ gba isinmi afẹhinti, ẹnikeji ni Ọgbẹni John Kennedy ti o jẹ ọkan ninu awọn Olugbimọ ile igbimọ nla, (Senator).

Ọgbẹni John Kennedy ni ibo na f'ọre fun, ti o si gba ibo tayọ Ọgbẹni Nixon. Eyi jẹ igba akọkọ larin ọdun mẹjọ ti ẹgbẹ Republican ti gba ipo na ki o to bọ lọwọ wọn si ọwọ ẹgbẹ Democrat, ẹgbẹ Oṣelu pataki meji ti o mbẹ nilẹ Amẹrika.

John Kenndey, a ba ẹ yọ.

OLORI ALUFA IJỌ AGUDA YIO GBA OLOTU IJỌBA GẸSI L'ALEJO

VATICAN CITY--A gbọ pe Olori Alufa Ijọ Aguda yio gba Olotu Ijọba ilẹ Gẹsi l'alejo ni asiko ti Olotu ijọba, Ọgbẹni Harold Macmillan, ba wa bẹ ilẹ Rome wo.

Ọgbẹni Macmillan yio de ilu Rome ni ọjọ kọkanlelogun oṣu November, lati ba Ijọba Italy sọrọ, fun ọjọ mẹta, ni ọjọ kejilelogun ni Pope John XXIII yio gba l'alejo.

## Awon Alabegbe Inu Ile Po Sa Lo

ILESHA-- A gbọ wipe Ọgbẹni Gabriel Agboọla, ti o to ọmọ ọdun marun-dinlogoji (35 years) ti o nṣiṣẹ iṣegun ni o pokunso sinu iyara rẹ ti ẹnikẹni ko si mọ ṣugbọn nigbati nwọn ko ri fun bi ọjọ mẹta, ni nwọn lọ sọ fun awọn ọlọpa pe awọn ko ri o.

Lẹhinna ni nwọn wa lọ ri oku rẹ ninu iyara rẹ nibiti o pokunso si, gbogbo alabagbe ile rẹ ni nwọn sa fi ile na silẹ.

A gbọ pe Ọgbẹni Agboọla yi ti du oye pataki kan lẹmẹta lati jẹ tiko bọsi. Orukọ oye na ni Lejọka Ilesha, oye pataki si ni iṣe. Gabriel Agboọla yi ku laini obinrin de ibi ti yio bi ọmọ.

NWỌN FI OBINRIN OYINBO SUN ẸSUN OLE

EKO- Ninu kotu kan niwaju adajọ nilu Eko ni nwọn ti fi obinrin Oyinbo kan sun ẹsun ole jija, pe o ji awọn nkan ti oni pọnun merin, ẹṣilẹ mẹtadilogun ati tọrọ (£4 : 17 : 3) ni ṣọbu Kingsway. O sọ wipe on ko jebi.

Adajọ gba iduro fun lori pọnun mẹdọgbọn (£25) ati Oniduro kan lori iye owo kanna.

Gigbọ ẹjọ rẹ di ọjọ mẹdọgbọn oṣu November, 1960.

## Isin Iranti Awon T'oku Si Ogun

EKO-- Eyi ni o jẹ iṣẹ ti Gomina Agba, Ọlọla Sir James Robertson ṣe gbẹhin nilẹ Nigeria ki o to wọkọ lọ silu rẹ ni ọjọ Atalata (Tuesday) ọsẹ yi.

Ni ọjọ ọṣẹ (Sunday) tokọja ni Gomina Agba ti gbogbo-gbo ilẹ Nigeria lọ fi ohun ọṣọ lelẹ nidi ere iranti awọn Ṣọja to ku s'ogun ni Idumọta, lẹhin isin ninu ile isin Ọlọrun nla ti Ẹhingbẹti l'Eko. (Cathedral Church of Christ)

Awọn enia pataki-pataki ti o wa sibi isin na ni Adajọ Agba Sir Adetokunboh Ademọla ati ọlọla iyawo rẹ, awọn Olotu ijọba ati awọn Ọga'gun ati awọn onipo nla ninu iṣẹ ijọba. Ẹniti o tun fi itanna ododo, ti nwọn fi ṣe ohun ọṣọ le'lẹ ni Alaiye-luwa Adenji Adele Keji, ọba ilu Eko, Ọga'gun agba awọn Ṣọja, Ọga gbogbo awọn ọlọpa ati Aṣoju ẹgbẹ awọn ọmọ-ogun atijọ. Olori gbogbo awọn Alufa ni o ṣe ibukun ikẹhin fun isin na.

IYA ATI ỌMỌ RẸ BU S'ẸKUN NI KOTU

MAKURDI - A gbọ wipe ariwo ẹkun ta gee ni Kotu ibilẹ ti ilu Makurdi nigbati nwọn ṣe idajọ ẹwọn ọdun meji fun Ọgbẹni Edwin Anigo fun ẹsun wipe o fi eru gbo'wo.

Ẹṣẹ ti nwọn ka mọ ọdaran na lọrun ni wipe o fi eru gba owo ogun ponun (£20) lọwọ Hibo Jukun kan pe on yio fi ba ṣe ọna ti nwọn yio fi da awọn ọmọ rẹ mejeji ti nwọn ju s'ẹwọn fun ẹsun abalafia ilu jẹ.

(Wo yoku loju ewe karun)

# ELETI - OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS: 28 Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM: "ELETI OFE, LAGOS" Phone 23370

VOL. XII. NO 672 SATURDAY NOV 19, NOV. 25, 1960

# ORIN L'O NSIWAJU OTE

Awọn Yoruba ni o ma sọ wipe "Orin l'o nṣiwaju otẹ," ododo ni ọrọ na. Ẹnyin ọkawe wa yio ranti pe ni nkan bi ọdun mẹta s'ẹhin nisisiyi, ti awọn enia wa ba nṣe nkan ayọ bi igbeyawo, oye jijẹ, tabi ikomọjade, ni awọn Onilu (Drummers) ma nlu ilu wọn na fi kọ orin ti a fi ṣe akọle oke wosika wa ọsẹ yi bayi.

A ṣe yi na o,
A o tun ṣe omiran si,
Ire mbọ, Ire owo,
ati be be lọ.

Ọpẹ ni fun Ọlọrun, Ọba Ọga Ogo, ilu wa ọwọn yi ti parada, o ti di ominira, ninu ọdun ti a wa yi, ọdun konigbagbe, 1960. Eyi nikan kọ, a ti di ẹniti yio ma ṣe ijọba wa funrawa, gbogbo iṣẹ ilu wa, ọrọ ilu wa, ati aṣẹ lori ilẹ wa Nigeria yi, ti kuro lọwọ ajeji, o si ti di ti arawa.

Ọmọ wa, ọmọ ilẹ Nigeria ni Olotu ijọba wa, Gomina Gbogbo-gbo ati Alaṣẹ Pataki fun ilẹ Nigeria ọmọ ilẹ wa ni. Gbogbo awọn opomulero ile iṣẹ ijọba wa ko si lọwọ ajeji enia mọ, awọn ọmọ wa l'o wa nibẹ. Ẹjẹki a fi ọpẹ fun Ọlọrun.

Eyi na to ni tiwa,
Awa l'a ni'badan,
To fi de Ogbomọṣọ,
Eyi na to ni tiwa.

Gbogbo ilẹ Nigeria di tiwa, o tọ, o si yẹ ki a sowọpọ ṣiṣẹ fun agbega ire ilẹ wa ti o kun fun oyin ati wara.

Alhamid lilahi.

# EGBE TI A NPE NI ZEALOT

Lati Ọwọ J. Awojulugbe

Bio ti wa lati atete koṣe, o mbẹ titi di isisiyi bẹni yio si ma ri titi yio fi de opin aiye ainipẹkun. Amin. Oluwa maṣe jẹki a fi ẹgbẹ-ke-gbẹ lo ominira ilẹ wa amin.

## ẸGBẸ ZEALOT

Ẹgbẹ ti a npe ni Silọti yi jẹ ẹgbẹ ti o lagbara gidigidi, ẹgbẹ na si jẹ ọkan ninu awọn ẹgbẹ Onigbagbọ igbani, ṣugbọn gbogbo ọna wọn ni o lodi papọ si ofin Ọlọrun. A.D. 29.

Ọpọlọpọ awọn Ju si gbogun ti ijọba Romu, papa ninu ọrọ isin igbagbọ, eleyi ni o si fa ogun airotẹlẹ ninu A.D. 70, ninu eyi ti a gbe wole isin Ọlọrun wọn lulẹ ninu ilu Jerusalemu, ẹgbẹgbẹrun aimoye ẹmi ni oku sinu ogun yi. Lati igba na, wọn ko tilẹ ri aye ati sin Oluwa ni ilu na mọ.

Orilẹ-ede awọn Ju si parun lati igbana nigbati ko si ile isin fun wọn mọ lati jọsin.

Lọṣe to mbọ ẹo mọ nipa awọn ẹgbẹ ile isin tio wa ninu ẹgbẹ yi o. Jesu wa ro ninu ara rẹ pe, ti awọn ẹgbẹ Silọti yi ba lọ di Alakoso ijọba igbana, ọna iparun ni yio mu wa si orilẹ-ede wọn. Dipo jagidi-jagan awọn ẹgbẹ Siloti yi, Jesu tete fi ẹgbọn mu awọn enia lati le yipada kuro lẹhin awọn ẹgbẹ Silọti yi, ati pe ki wọn ba le tẹ si ọna Ọlọrun ki wọn si le ni ifẹ fun ara wọn pẹlu.

On si nkilọ fun wọn fun ewu nla nla ti o mbọ sori ilẹ na, ati iya ti yio fi jẹ wọn.

Ṣugbọn ni igbẹhin, awọn ẹgbẹ Silọti bori nigbogbo ọna wọn, lẹhin igbati wọn fi aye silẹ fesu ti wọn kan Olugbala wọn mọgi loju wọn ninu ọdun A.D.

Nigbati Jesu wa laiye, o ri pe awọn enia ni ẹmi ikorira pupọ fun ofin awọn ara Romu, eyi mu ki nwọn ma tapa si awọn ara Romu. Awọn ẹgbẹ ti a npe ni Silọti yi nṣe ni wọn ma nfi ina si ẹtu ọrọ na ati papa wọn wa ọrọ ati ti ijọba Romu ṣubu lati ọwọ Olori wọn ti a npe ni Judasi, ọrọ yi bẹrẹ si nṣẹlẹ lati igbati ati mu Akẹlọ kuro loni oye rẹ, nibiti o gbe nṣe Alakoso agbegbe Judia gbogbo. Ẹgbẹ Silọt mura ija gidigidi, nwọn nṣe Alakoso awọn ti o ni ẹmi ọtẹ pẹlu ara wọn lati ṣe jamba yi fun ilu Romu. Simọni, ọkan ninu awọn ọmọ ẹhin mejila si jẹ ikan ninu ẹgbẹ Silọti, ṣugbọn ko ti de ọdọ Jesu nigbana.

# Oda Omi Da Nilu Ijebu-ode

IJẸBU-ODE- Asiko yi le koko nilu Ijẹbu-Ode fun ọda omi ti o da depo ti o fẹrẹ ma le ku enia kanṣoṣo ninu odidi agbole nitoripe bi ilẹ ba ti mọ ni olukuluku awọn enia yio gbe kete tabi garawa d'oriko ọna odo lati wa omi pọn wa sile.

Awọn enia na yio si rin irin bi ibuso meji ki nwọn to le ri omi. Koroba omi kan ti nwọn ti nra ni kọbọ kan (1d) ti pada di tọrọ (3d) nisisiyi.

Awọn Onimoto akẹru ti bẹrẹ si fi omi ṣ'owo, nwọn nlo fi moto won pon omi wa ta nilu Ijẹbu-ode.

# Obiri Aiye Nyi

NORWAY – Ọmọba obinrin ti oruko rẹ njẹ Astrid, Ọmọba obinrin, Ọba Olav ti ilu Norway ni a gbọ pe yio ṣe igbeyawo pọ pẹlu enia ti ki iṣe ọmọba. Ẹniti ọmọba'binrin Astrid, ọmọ ọdun mejidilogbọn na fẹ la ṣe igbeyawo pọ ni Ọgbẹni John Martin Ferner, ọmọ ọdun metalelogbọn, ti o ti nṣiṣẹ ni ile oja baba rẹ ni Oslo, Olu ilu Norway. A gbọ wipe ọjọ igbeyawo wọn na ni ọjọ kejila oṣu Januar, oṣu January ọdun ti o mbọ. A gbọ pe ẹgbọn ọmọba na obinrin ti oruko rẹ njẹ Ragnhild ko fẹ Ọmọba Ọkunrin, ẹniti o wu ni o fẹ.

Eyi ni a fi wipe obiri aiye nyi! nitoripe ati gbọ wipe awọn Ọmọba'binrin ilẹ awọn Oyinbo ko jẹ fẹ ẹlomiran tabi enia lasan ti ki iṣe Ọmọba ni Ọkọ.




## Olotu Ijoba India Goke Agba

NEW DELHI - Ni ọjọ Monday ọse yi ni Olotu ijọba ilẹ India, Ogbẹni Jawaharlal Nehru di ọmọ ọdun mọkan-le-ladọrin ni ọjọ ori rẹ. (71 years)



Kọṣe rohin ni ọrọ'ọpọ awọn ọmọde ti nwọn rọ di ilẹ rẹ, ti ko si aye ti enia le gba kọja niwaju ile Olotu ijọba, awọn ọm na wa ba yọ ayọ ọjọ ibi rẹ.

Ọlọjọ ibi, ọjọ ayọ.

## Kosi Ilu To Gba Gbere Mo

ABẸOKUTA - Ni ile ẹjọ, Kotu Ake ni Abẹokuta ni a gbọ pe nwọn ṣe ẹjọ kan ti ọrọ ẹjọ na mu wa kọ akọle irohin wa yi.

A gbọ pe obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Omitayọ, onişowo ni iṣe ni Igbore, nilu Abẹokuta, on ni ẹniti o pe ọlọpa ọba kan lẹjọ si Kotu wipe ki ọlọpa na kuro lori ilẹ on ni Igbore.

Ọlọpa fi ake kọ'ri pe ilẹ ti on ni ilẹ na, nitoripe on j'ogun rẹ ni, ko si ẹniti o le gba lọwọ on.

Nigbati awọn ẹlẹjọ mejeji ro ẹjọ wọn tan niwaju Adajọ Kotu ibilẹ Ake "Onipo Kini" Oloye V.A Ilọri sọ wipe on gba pe ilẹ na ki iṣe ti ọlọpa, atipe ọlọpa na sa agbara aye rẹ gẹgẹbi ọlọpa ọba lati fi tu Iyafin Omitayọ jẹ ni. Nitorina ki o lọ san owo ponun marun-di-logorin (£75) fun Iyafin Omitayọ.

**OKU'JA WOLU**

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE SE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Yin
Sinna Iwe Irohin
ELETI OFE

## Ija Ile Da Ijongbon Sile

ONITSHA — Awọn enia marun ni a gbọ wipe o ti ku lori rogbodiyan ọrọ ilẹ ti o ti wa larin awọn ara Onitsha ati awọn ara Obosi lori wipe emi l'oni ilẹ, iwọ l'o ni ilẹ, lati nkan bi ọdun mẹdogun s'ẹhin.

A gbọ wipe idajọ Kotu sọ pe ki awọn apakan kuro lori ilẹ na, ṣugbọn awọn enia na kọ jalẹ ; e awọn koni pa aṣẹ kotu mọ.

Nigbati awọn Ọlọpa de, ni awọn enia na nṣ'ekọ si wọn ki a ma fa ọrọ gun, nigbati ara awọn ọlọpa ko gba mọ ni nwọn ba ni lati sina fun wọn. Ṣugbọn titi di asiko ti a nkọ irohin yi nkan na koiti rogbo.

## Iya Ati Omo Re Bu Sekun Ni Kotu

(O bere loju ewe kẹta)

Ọdaran yi sọ wipe on yio fi owo na fun adajọ Kotu ibilẹ, "Onipo kẹrin' (Grade "D)" ki o fi le da awọn ọmọkunrin meji ti nwọn ju s'ẹwọn oṣu mejimeji fun ẹnikọkan wọn silẹ.

Awọn ọmọ jẹ ọmọ Hibo Jukun, nigbati ẹrọ na ko jẹ bẹ mọ ti ko si da owo pada fun olowo, ni ọrọ na fi de ọdọ ọlọpa. Nigbati adajọ da lẹbi ti o si ṣa konko ẹwọn ọdun meji mọ lara ni iyawo ati awọn ọmọ rẹ bu s'ẹkun ti nwọn si gbe arawọn ṣonlẹ.

Lẹgan ni awọn ọlọpa le wọn niwaju

# Dokita Mbadiwe Tun Di Alakuko (N. C. N. C.)

EKO - Ninu ipade awọn igbimọ Alaṣẹ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C) ti nwọn ṣe kọṣẹ tokọja ni a ti gbọ wipe, awọn igbimọ na ti ro ọrọ iwe ẹbẹ ti Dokita Mbadiwe kọ si wọn siwaju-s'ẹhin, nwọn si gba pada sinu ẹgbẹ na l'ori adehun pe ki o lọ pa ẹgbẹ D.P.N.C ti o da silẹ tì, ki a si gba wọn laye ki awọn ọmọ ẹgbẹ na le wọ ẹgbẹ N.C.N.C funrawọn.



O ta siwa leti fenren wipe awọn ọmọ ẹgbẹ D.P.N.C ti Dokita Mbadiwe da silẹ na yio ṣe akanṣe ipade lori ọrọ na ati wipe o si dun mọ wọn ninu ti nwọn gba aṣiwaju ẹgbẹ wọn pada sinu ẹgbẹ Alakukọ (N. C.N.C).

Nkan keji ti awọn igbimọ Alaṣẹ (N.C.N.C) ẹgbẹ Alakukọ ṣe ti a gbọ niti ẹgbẹ awọn ọdọmọkunrin ti nwọn npe ni Zik's National Vanguard ti nwọn pinnu lati dapọmọ ẹgbẹ ti N.E.P.U. ki oruko rẹ si ma a jẹ N.C.N.C. Youths Vanguard.

Dokita Mbadiwe tun pada di Alakukọ o.




# IPADE AWON OLOTU EKO NI ILU OYINBO



Ninu ipade ti awọn Olotu Ẹkọ iwe gbogbo agbaiye se nilu Oyinbo ninu oṣu July, 1959, ni ati nwo Ọgbẹni T. O. Ejiwunmi Alabojuto ẹkọ (Inspector of Education) ti ipinlẹ Iwọ-orun Nigeria, ti o mba Ọgbẹni Geoffrey Lloyd jọwọ po nibi apejọ nla kan ninu ile nla Lancaster ni London.

Awọn enia ti o pade ninu ipade na to adọjọ enia lati orisirisi ilu. Ipade na dun o si larinrin.

## Ibo F'ore Fun Egbe Demo

DENMARK — Ẹgbẹ Demo ti ilu Denmark ti o ti nṣejọba fun odun mejẹ ṣeyo tun bori ninu ibo ti awọn di gbẹrọko mela kan arawọn ni ọjọ Tuesday, awọn ti o koko gba ibo ju ẹgbẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun lọ nilu Denmark.




## Nwon Fi Olopa Oba Marun

SUN ESUN AGB-OWO-ẸHIN

EKO - Ni Kotu Ikeja ni Saka Salawu t'owa-moto ak'ẹru ti ro'jọ m ọ ọlọpa ọba marun wipe lẹhinti nwọn ti gba owo ponun meji lọwọ on ni ọna Eko si Ikorodu, ni awọn ọlọpa na tun da moto on duro ti nwọn si bere owo ti o ku lati fi kun ponun meji ti won ti gba. On si fun won ni ṣile mẹwa pepa oni-ṣili marun-marun ti nwọn ti sami si lara ni Ṣọbu awọn ọlọpa-inu, nisoju awọn ọga ọlọpa-inu mẹta.

Saka njẹri lori ẹsun agb'-owo ẹhin ti nwọn fi awọn ọlọpa marun sun, awọn ọlọpa na ni James Kalẹjaiye, Danzumi Dankano, Iga Emafo, Shanu Ọkẹjẹ ati Clement Uzoka.

Ẹjọ na tun di ọjọ keta-le-logun oṣu yi.

## Ejo Apania Bere Ni Kotu

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Ẹniti o jẹri gbẹhin ni Raimi Amusa ti o ngbe 22, Agbole Abari o sọ pe on l'o mu ọdaran na nigbati o nsalọ. Bi on ti fẹ mu u, o fi ọbẹ deruba on, ẹjẹ wa lara ọbẹ na nigbati on sa lọ. Bi on ti fẹ mu u o fi ọbẹ deruba on, ẹjẹ wa lara ọbẹ na, nigbati on raye fun ni igbaju gbigbona kan, ni on to le gba ọbẹ lọwọ rẹ, on si mu lọ fun ọlọpa.

Iwadi siwaju yio bẹrẹ ni ọjọ kọkan-le-logun oṣu November yi.

## OLOYE AKINTOLA ṢE APONLE GOMINA AGBA

(O bẹrẹ loju ewe keji)

ṣe aponle Gomina na, nitori ọrọ rẹ ti o sọ wipe, gẹgẹbi enia nla ti o ṣe iṣẹ rere nla fun ilu nla ni Sir James Robertson, Gomina Gbogbo-gbo ilẹ Nigeria ṣe.

Olotu sọ wipe ni asiko iṣẹ rẹ ni o mu iyipada rere wọ inu awọn Oyinbo ati awọn enia ilẹ Nigeria.



Ọlọla Gomina Agba dupe lọwọ Ijoba Iwọ-orun fun ẹye ti nwọn ṣe fun u. O si mu da awọn Ọba ati Ijoye pelu awọn enia ipinlẹ Iwọ-orun loju pe on yio ma'a fi ire ilẹ Nigeria s'ọkan.

Ninu awọn enia jankan-jankan ti o wa sibi apejọ na ni Ọlọla Sir Adesoji Aderemi, Gomina ipinlẹ Iwọ-Orun, Olotu ijọba Apapọṣe tilẹ Nigeria, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, awọn Oponmulero iṣẹ ijọba, awọn Ọba ati awọn Ijoye.

## Erin Wo L'oke Amilala !

Ebutemetta-Pagi 'ari Igi da!
Babaawo a ku,
Gbagbun a f'orun,
Iku apa adahunșe.

Ilu d'oro, iku ș'ika iku pa Joseph Ș...kẹ Șiwọ ku, eni rere lọ.

A gbọ jugbanu n i iku Ọgbẹni Șiwọku, Alakoso le itaja "Ẹgba Trading Aradan Stores" ni Ebute-Metta, fun t'ọmọde-tagba, ọkunrin ati obinrin, nitoripe oninurere enia ni ișe nigba aiye rẹ. Ọgbẹni J. S. Șiwọku f'aiye silẹ nigbati o d'agba di ẹni ọdun mẹrin-le-lọgọta.

Awa "ELETI-ỌFẸ" ki Iyawo rẹ, obinrin r e r e, abiwa pẹlẹ ku afẹku ọkọ rẹ nwọn, a si ki awọn ọmọ rẹ ati ẹbi rẹ ku ilode eni wọn.

KI ỌLỌRUN GBE
SI AFẸFẸ-RERE

## Ebun Owo Odun

EKO — Awọn Oyinbo Onișowo U.A.C. ni a gbọ wipe nwọn yio fun awọn ọșișẹ wọn ni owo ọsẹ kọkan fun ẹbun ọ d u n Keresimesi.

Awọn Alakoso ile ișẹ U.A.C. șe ipinnu yi lori iwa ati ișẹ r e r e awọn ọșișẹ n a ninu ọ d u n to kọja.

Ni ọjọ kẹrin-di-logun oșu December, ni nwọn yio san owo ọsẹ kọkan fun olukuluku awọn ọșișẹ wọn.

Eyi wu wa o.

## Nwon Da Mabayoje Sile Ni Kotu

IJẸBU-ODE- Mabayọjẹ Talabi, ti o nșe ișẹ agbẹ roko, ti nwọn fi sun ẹsun wipe o șeși yinbọn pa Adenuga Bajo, ni ọjọ kẹtadi-lọgbọn oșu A u g u s t, ni adugbo Okeigbo, nigbati nwọn nșe ọdun Orișa Ogun

Adajọ Kotu Ijẹbu-ode da silẹ pe ki o ma lọ ni alafia nigbati ko s i ẹri pataki.

## Onisegun Daku Si Kọtu

SAPẸLẸ. Garuba Katsina, ti o pe ara rẹ ni Adahunșe șubu lulẹ ti o si daku sinu Kọtu nigbati adajọ șa konko ẹwọn ọ d u n mẹrin mọ lara nigbati o jẹbi ẹsun ole.

Awọn ọlọpa s ọ wipe awọn așọ ti awọn ole ti ji ko nile onile ni nwọn ri lọwọ Garuba, ọdaran na. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti gbe lọ sile iwosan.

## Moto Olopa Gb'ina

IBADAN- Mọto a w ọ n ọlọpa kan ti o ko enia mẹta nlọ si Ș ọ b u awọn ọlọpa fun ibere nipa i j a kan ti o șẹlẹ ni o gbina l'oju ọna Opopo Onireke nilu Ibadan l ' a l ẹ ọ j ọ Monday.

A gbọ wipe awọn ọlọpa yio șe iwadi ohun ti o fa sababi ina aburadi ti o jo ọkan ninu mọto wọn na.

## Osadebay Di Alakoso Igbimo Nla

EKO- Ninu i p a d e i l e Igbimọ nla ti nwọn șe nilu Eko ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọjọ kẹtadi-logun oșu yi, ni awọn agbagba Olugbimọ na panupọ yan Oloye Dennis C h u k u d e Osadebay si ipo Alakoso Igbimọ (President of the Senate) d i p o Ọlọla n l a Dọkita Nnamdi Azikiwe ti o ti pada d i G o m i n a Gbogbo-gbo ati Alașẹ Pataki ilẹ Nigeria.

Ẹniti o damọran yiyan Oloye Osadebay ni Olugbimọ Zanna Medella Abba Sherif.

Lẹhin ti nwọn yan Oloye Osadebay s'ori aga Akoso igbimọ na ni Oloye n a dupẹ lọwọ gbogbo igbimọ, o si wipe ișẹ ti a gbe l e on lori n a w u w o jọjọ, nitoripe ki ișe ohun ti o rọrun lati ki ẹsẹ bọ bata ti Ọlọla nla Dọkita Azikiwe bọ silẹ, nipa bẹ, nigbati on boju wo aga Akoso na, ẹru jẹjẹ ba on. Șugbọn on yio gbiyanju lati mu ipo n l a na duro fun i r ẹ p ọ i l ẹ Nigeria.



Lehinna ni Igbakeji Alakoso (Deputy President) Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, Ọba Eko, ki Oloye Osadebay ku orire, o si sọ ọrọ apọn'le nipa rẹ.

## Nwon Yan W.A.Popoola Sinu Igbimo

Awọn enia to wa ni Ward Kẹjọ ilu Agbado Station se ipanupọ ninu i p a d e tokọja lati yan Councillor W. A. Popoọla lati tun pada si ile Igbimọ Ẹgba Ifọ. Fun ibo miran ti a o tun di laipẹ yi.

Ọgbẹni Oloye L a w a l Oloyede dupẹ lorukọ awọn enia ti yio dibo na wipe Ọgbẹni Popoọla jẹ Așoju rere f u n wa, ekini, n i asiko tirẹ ijọba fun wa ni aye ki mọto le ma k ọ j a lori irin Railway, ekeji, ile Ibimọ fun awọn Alaboyun eyi ti wọn yio bẹrẹ n i ọsẹ to mbọ fun ati m a kọ ile na. Gbogbo wa si dupẹ lọwọ Așoju rere na wipe, ki Ọlọrun ko ran lọwọ lati șe eyi to ju bẹ lọ fun wa (Amin). A o șe ipade ni ita Balẹ loni.

Lẹhin na n i Ọ g b ẹ n i Oseni Lawal Abogun-loko eniti ise Amugba-mẹgbẹ, Ẹgbẹ Agbado Ward kejọ, T a x Payers Association wipe, Ki a p a I g b i m ọ Adele Balẹ, Care-taker Commitee rẹ, ki asi yan awọn ẹlomiran s i Igbimọ Balẹ ati Council, ki ọjọ I b o na to pe, awọn to wa si ipade na ni:-

Ọgbẹni L a w a l Oloyede, Chairman, Ọșeni Abogunloko. C. O. Olowu, Chief Imam Lamirigi, Alhaji Tijani, Akifẹnwa, L a w a l Okelọla Ẹkẹrin - Owẹ, G. Musitafa ati ọpọlọpọ awọn enia nla nla.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street, P. O. Box, 467, Lagos, Phone 23370